# IPE MOSE NIBI TI IGBẸ́ GBÉ N JÓ

**Ẹksodu 3:1-22**

**ẸKỌ 48 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: “Nitori ailábámọ̀ li ẹ̀bun ati ipe Ọlọrun” (Romu 11:29).**

**I Ifarahan Ọlọrun fun Mose**

1 Mose n ṣọ́ agbo-ẹran Jẹtro ni agbegbe Oke Sinai, Ẹksodu 3:1; Gẹnẹsisi 39:1-6, 22, 23; 1 Samuẹli 16:19-23; Galatia 1:17

2 Ọlọrun fara hàn ninu igbẹ ti n jó, eyi rú ọkàn Mose soke lati ṣe ọfintoto, Ẹksodu 3:2, 3; Luku 19:2, 3; Johannu 1:46

3 Wiwò ti Mose lọ wo ifarahàn agbara Ọlọrun yii fun Ọlọrun ni anfaani lati pe e, Ẹksodu 3:4; Johannu 1:47-49

4 Ọlọrun fi ara Rẹ̀ hàn Mose, eyi si mu ki Mose fi tọ̀wọtọ̀wọ tẹriba, Ẹksodu 3:5, 6; Jọṣua 5:13-15; Daniẹli 10:8, 9; Ifihan 1:17

**II Ifihan Awọn Ipinnu Ọlọrun fun Mose**

1 Ọlọrun fi ifẹ Rẹ̀ si awọn Ọmọ Israẹli hàn: O ti **ri**; O ti **gbọ́**; O ti **mọ̀**; O si **sọkalẹ,** Ẹksodu 3:7, 8; Orin Dafidi 139:1-12; Gẹnẹsisi 18:21

2 Ọlọrun fi ipinnu Rẹ̀ hàn nipa awọn eniyan Heberu, Ẹksodu 3:9, 10; Iṣe Awọn Apọsteli 7:29-35

**III Fifi Agbára Ayeraye Ọlọrun Hàn Fun Mose**

1 Mose bẹ̀ru nitori iwuwo iṣẹ naa, o mọ ailagbara rẹ̀, Ẹksodu 3:11

2 Ọlọrun mu ki ifẹ ati iranwọ Rẹ̀ nigba gbogbo fun Mose ki o da a loju, Ẹksodu 3:12; Jeremiah 1:7, 8

3 Mose beere aṣẹ lọwọ Ọlọrun, o si ri ifarahan ti o ga nipa orukọ ati wiwà Rẹ̀ titi ayeraye, Ẹksodu 3:13-15; Isaiah 6:1-5; Marku 12:26, 27

**IV Iṣẹ́ ati Aṣẹ ti Ọlọrun Kọ́kọ́ fi le Mose Lọwọ**

1 A sọ nipa iṣẹ-iranṣẹ naa fun Mose, Ẹksodu 3:16, 17; Iṣe Awọn Apọsteli 26:15-18; Orin Dafidi 103:7

2 A paṣẹ fun Mose lati fara hàn niwaju Farao, Ẹksodu 3:18

3 Ọlọrun kilọ fun Mose tẹlẹ nipa agidi ọkàn Farao, O si sọ bi a o ti ṣe gbà Israẹli là, Ẹksodu 3:19-22; Isaiah 6:9, 10

## ALAYE

Nisisiyii a ri Mose, ẹni ti yoo wá di aṣiwaju Israẹli, ninu aginju lẹba Oke Sinai, o n ṣọ́ agbo agutan Jẹtro baba aya rẹ̀, eyi si ni igbesẹ ikẹyin ninu ẹkọ kikọ́ ti Mose gbà lọwọ Ọlọrun.

Ẹni kan ti sọ bayii pe, “Eniyan le ni lati fi ipo ainilaari ṣe atẹgùn de ipo okiki,” a si ri pe otitọ gan an ni ọrọ yii pe awọn ti Ọlọrun yoo lò ni lati kọ́kọ́ wà ni ipò ti o dabi ẹni pe o jinna si Ọlọrun – nigba miiran ninu “aginju ati aṣalẹ̀,” nigba miiran ninu afonifoji ipọnju ati arò, nigba miiran ninu hila-hilo ati aniyan. Igba ẹ̀kọ́-kikọ wọnyii jẹ apa kan eto Ọlọrun lati mu ni sun mọ tosi Rẹ̀; ṣugbọn nigba pupọ ni a ti ri pe nipa ikuna, aifara-balẹ, ailera tabi ijafara wa ni a ti n pade wọn.

Ni ti Mose boya ohun ti o mu akoko yii de ni sisare rẹ̀ lati ṣaaju akoko Ọlọrun lati gba ipò ti oun rò pe o jẹ ifẹ Ọlọrun fun un. O ri iwa aitọ́ ti a ṣe si ọ̀kan ninu awọn eniyan rẹ̀; bi o si ti jẹ pe ẹni ti a fi iya jẹ naa ko si ni ipò ati gba ara rẹ̀ silẹ, Mose gba ọran naa kanri. Boya o ro pe nipa bẹẹ oun le gbe ọ̀tẹ̀ dide si gbogbo iwa-ikà ti a ṣe si awọn eniyan rẹ̀ ki oun si dá Israẹli nide kuro ninu ajaga ẹrú. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ọna tabi èto Ọlọrun, bẹẹ ni ki i si i ṣe akoko Ọlọrun. Ọlọrun fẹ ṣe e lọna ti ẹnikẹni kò fi ni gba ògo tabi ọlá fun idasilẹ naa. Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ sin In ki wọn si bu ọla fun Un, ati ki O ba le kọ́ wọn ni isin naa, O pinnu lati dá wọn nide nipa Ọwọ ipá ati agbara ti Rẹ̀.

Otitọ ni ipè Mose. O mọ ipè Ọlọrun ninu ọkàn rẹ̀, ni ibẹrẹ o si n fẹ yara dahun. Ṣugbọn iwarapapa rẹ̀ ko jẹ ki awọn eniyan rẹ̀ naani rẹ̀, nipa bẹẹ o di alailagbara lati le ran wọn lọwọ fun igba diẹ. Nigba ti a ba ṣaaju Ọlọrun, bi o tilẹ jẹ pe ninu ohun ti o da wa loju pe ifẹ Ọlọrun ni, awọn ẹlomiran kò ni le ri ohun ti awa ri daju gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun fun wa. Ṣugbọn nigba ti a ba duro de Ọlọrun lati ṣe eto Rẹ̀ ni finnifinni ti O si fi wa si àyè ti Oun ti pese silẹ, gbogbo eniyan yoo ri ọwọ́ Ọlọrun ninu ọran naa, wọn yoo si yé ipè wa sí.

Ifarahan Ọlọrun ninu igbẹ́ ti n jó ni yoo jẹ ohun idaniloju kan fun Mose pe Ọlọrun ti ran an ati pe Ọlọrun yoo wà pẹlu rẹ̀ nigba gbogbo. A le fi wé Israẹli ninu oniruuru iṣẹ́ ati inunibini rẹ -- ninu iná, ṣugbọn kò jona. O tun jẹ apẹẹrẹ ijọ -- laaarin inunibini nigba kuugba, laaarin awọn ọta, ninu ojiji ikú, ṣugbọn kò parun. Lọna kan, o jẹ apẹẹrẹ olukuluku ọmọlẹyin Kristi – ti a ṣe inunibini si ṣugbọn ti a ko kọ̀ silẹ; ti a rẹ̀ silẹ ṣugbọn ti a kò parun; ti o n rin laaarin ina, sibẹ iná kò jó o.

Nigba ti Mose ri igbẹ ti n jó naa, o yí pada si apa kan lati wo ki ni o jẹ́. Akéwi kan, ti a kò mọ orukọ rẹ, sọ daradara nipa eyi nigba ti o wi pe:

**"Lokere'nu aṣalẹ ni a ri i,**

**Bi ọmọ anikan-da-jẹ,**

**Ti o n lọ siwa lọ sẹyin,**

**Igi ẹgun kan wà ninu iná,**

**Ti n jù sihin jù sọhun lai jona:**

**Ta ni yoo rekọja lai wo'bẹ?**

**Nin'oko tutu lẹba oke**

**L'awọn agutan fọ́n ká si**

**Lati wá ounjẹ wọn;**

**Pẹlu gbogbo ọkàn**

**Oluṣọ-agutan n b'Ọlọrun sọrọ**

**O si fi'rẹlẹ juba."**

Ẹni ti "o kuku yàn ati mã bá awọn enia Ọlọrun jiya, jù ati jẹ fãji ẹ̀ṣẹ fun igba diẹ; o kà ẹ̀gan Kristi si ọrọ̀ ti o pọju awọn iṣura Egipti lọ," gbagbe abojuto iba agutan diẹ ti ayé yii o si kọ oju rẹ̀ si Ọlọrun. Ati nitori ti o ṣe bẹẹ, Ọlọrun le ba a sọrọ ki o si pe e fun iṣẹ pataki kan. Melomelo ninu wa ni o ti padanu awọn ibukun ti Ọlọrun i ba fun wa nitori a ko "yi si apa kan lati ri" igba ti Ọlọrun sún mọ wa!

Ifihan yii ti ọdọ Ọlọrun tikara Rẹ̀ wa, Ẹni ti o fara hàn ninu iná ti n jó. Nibi ti Ọlọrun ba si wà eniyan ni lati bọwọ fun Un. A paṣẹ fun Mose pe ki o bọ́ salubata ẹsẹ̀ rẹ̀ niwaju Ọlọrun rẹ: Ọlọrun Olodumare, Oluwa Ọlọrun Jehofa, Ẹni nla ti i jẹ EMI NI! Lọna kan naa ni Jọṣua pẹlu bọwọ fun Ọlọrun nigba ti o pade Oluwa ni pẹtẹlẹ ti o doju kọ Jẹriko.

Iṣẹ ti o tobi gidigidi ni a fi fun Mose. Ọran nla ni n bẹ, ẹrù naa si wa lori ẹni ti Ọlọrun yoo yàn lati dari awọn eniyan Rẹ̀ lọ si Ilẹ Ileri naa. A ko le ba Mose wi ti o sọ pe: "Tani emi?" Nigba ti Ọlọrun ba n pe ni si ipo giga ninu iṣẹ Rẹ̀ a ki i ro pe a ti tó tan fun ra wa. Ẹran ara maa n fa wa sẹyin lati doju kọ iru iṣẹ nla nlà bayii. Paulu Apọsteli sọ nipa ipè ti rẹ̀ pe, "Aigbọdọ-máṣe wà lori mi; ani, mo gbé! bi emi kò ba wasu ihinrere" (1 Kọrinti 9:16). Ṣugbọn iranlọwọ Ọlọrun maa n tẹle aṣẹ ti O ba pa fun ni, yoo si fun wa ni ọgbọ́n ati agbára lati ṣe iṣẹ Rẹ̀.

Itunu nla ati imulọkanle wa ninu idahun ti Ọlọrun fun Mose. "Nitõtọ emi o wà pẹlu rẹ." Itumọ eyi ni pe, Mose yoo jẹ́ iranṣẹ, ki yoo jẹ́ oluwa. O fi hàn pe iṣẹ naa yoo yọri si rere dandan, oore-ọfẹ ati agbára yoo si to fun un. O tun tumọ si pe bi Farao paapaa tilẹ doju kọ ẹ̀bẹ̀ naa, Mose yoo tọ̀ ọ lọ lati ba a sọ̀rọ. Bawo ni i ba ti dara to lati ni iru ọ̀rọ idaniloju bayii nigba ti a ba n lọ lati bá awọn ọta ododo ja! "Nitõtọ emi o wà pẹlu rẹ" jẹ ọrọ aṣẹ lori gbogbo ọ̀na iṣoro ati ilẹkun ti o tì, okun ni o jẹ nigba ti ogun ba le, iṣẹgun si ni nigba ti "ọta yio de bi kikún omi."

Awọn ẹsẹ Iwe Mimọ́ kan wà ti awọn alaigbagbọ́ fi mimọ̀-ṣe-aimọ̀ nipa rẹ̀, lori eyi ti wọn maa n saba gun le ninu àtakò kikan wọn pe alaiṣootọ ni Ọlọrun. Ọkan ninu wọn ni awọn ẹsẹ diẹ ti o kẹyin ẹ̀kọ́ wa. Ọlọrun sọ ni ṣoki fun Mose ọna ti a o fi gba Israẹli là, pe wọn o tọrọ nnkan lọwọ awọn ara Egipti wọn o si fi bẹẹ kó orilẹ-ede naa ni ẹrù lọ. Awọn alaigbagbọ́ maa n tọka si eyi pẹlu iyọṣuti si, pe awọn alaiṣe ara Egipti ni a fi bayii jẹ niya nitori iwọra ati ofin awọn ọba ikà ti o wà lori wọn, labẹ awọn ẹni ti awọn ara Egipti paapaa le maa jiya.

Ṣugbọn eyi kò yẹ ki o mu ariyanjiyan lọwọ. Awọn Ọmọ Israẹli jẹ ominira ti a sọ di ẹrú nitori awọn ara Egipti bẹ̀ru agbara awọn eniyan naa ti i ṣe oloore wọn. Wọn n kó wọn ṣiṣẹ lai sanwo fun wọn – ani lai ni ohun elo iṣẹ paapaa fun sáà kan – a si ni lati tun pa awọn ọmọ wẹẹrẹ wọn run. Ẹni kọọkan ni orilẹ ede naa ti o jere ninu iwa-ika wọn yii ni o jẹ Israẹli ni gbese.

Itumọ yiyá, bi a ti lò o nihin, yoo yanju iṣoro naa. Ohun ti o tumọ si ni lati **beere**. Ọlọrun sọ fun awọn Ọmọ Israẹli lati beere ohun ti i ṣe ẹtọ wọn fun iṣẹ wọn, pẹlu ọkàn yii ni wọn si fi beere; ko si si ẹni ti o ka a si nnkan ti a yá lò, yala laaarin awọn Ọmọ Israẹli, tabi awọn ara Egipti. O jẹ ti wọn nitori wọn ti ṣiṣẹ fun un -- wọn tilẹ ṣe ju bẹẹ. Bi a ba ṣiro iye owo-ọ̀ya wọn perepere nigba ti wọn fi Egipti silẹ, gbese pupọ ni yoo wà lọrun Egipti sibẹ. Ọlọrun lo jẹ ki wọn san an pada fun awọn Ọmọ Israẹli lọna bayii.

## AWỌN IBEERE

1 Nibo ni Mose wà nigba ti o gbọ́ ipè Ọlọrun?

2 Ki ni Mose n ṣe nigba naa?

3 Ta ni awọn eniyan Ọlọrun miiran ti o la iru idanwo bẹẹ kọja ki Ọlọrun to le lò wọn daradara?

4 Ki ni ifihan iyanu ti Ọlọrun fi mu Mose yi pada kuro nibi iṣẹ rẹ̀ ojoojumọ?

5 Ki ni Mose ṣe nigba ti o mọ̀ pe Ọlọrun lo n sọrọ?

6 Nigba ti Ọlọrun sọ ohun ti Mose yoo ṣe fun un, ki ni Mose wí?

7 O ha tọ́ fun Mose lati sọ ohun ti o wi; ki ni idahun ti Ọlọrun fi fun un?

8 Orukọ wo ni Ọlọrun fi pe ara Rẹ̀ ni akoko yii?

9 Ki ni a rò pe iran àbami yii yoo tọka si fun Mose ninu awọn ọdun ti yoo tẹle e?

10 Sọ ni kikún, ohun ti o wà ninu eto Ọlọrun fun Israẹli, bi a ti sọ ọ fun Mose nihin.